# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AYIE, TENI GBOGBO LAWA

NO 884 THURSDAY DECEMBER 31 1964 (2D


## Awọn Ọmọ Ẹgbẹ UPGA Meje Wa Ni Itimole

IBADAN:— Ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kọkandinlogbọn oṣu yi ni Adajọ ile ẹjọ ibi ti nwọn tise ẹjọ awọn Ẹha na Ọgbẹni Thomas Gomes sun ọjọ ẹjọ awọn ọmọ ẹgbẹ itesiwaju meje ti nwọn mu lori ẹsun pe nwọn nja ija igboro eyi to jẹ pe o le fa ohun to lewu lọwọ si ọjọ kẹrin oṣu to mbọ yi.

Awọn ọmọ ẹgbẹ ilọsiwaju ilẹ Naijiria meje ti nwọn fi ẹsun na kan ni Musa Obişẹsan Ra'mi Akaide Owoade Egbeleke Lamidi Obişẹsan Jimọ Obişẹsan ati Adisa Obişẹsan. Ninu ẹsun ti Agbẹjọro fun ile ẹjọ na fi kan awọn ọmọ ẹgbẹ UPGA na nipe ni ọjọ kọkanlelogun osu yi pe nwọn lọ kolu Minista Alamojuto eto irohin fun Ijọba ipinlẹ Iwo Orun ni adugbo Ita Balẹ, Olugbode, Ibadan.

Lẹhin eyi ni Agbẹjọro fun awọn ọmọ ẹgbẹ UPGA na Alhaji Busari Obişẹsan so fun Adajọ na lati jẹki nwọn gba iduro awọn ọmọ ẹgbẹ na. Şugbọn Adajo ile ẹjọ na taku lati gba iduro wọn eyi ti o fi sọ pe ki nwọn lo ti wọn mole titi di ọjọ kẹrin oṣu to mbọ yi.

### "Aja Kọ Imi Ẹlẹdẹ, Ẹlẹdẹ Kọ Imi Aja"

# EKO KỌ IBO SILE !



EKO:— Ọrọ di ki onile o gbele nigbati gbogbo awọn ara Eko fariga ni kutukutu owuro ana ọjọ ojo'Ru ti ise ogbonjo oṣu yi ti gbogbo awọn e ia Naijiria nlati dibo ti gbogbo won si dake sinu ile ti ẹnikan ko jade sita lati lo dibo gẹgẹbi eto ti o ti wa nilẹ lati bi oşu kan şẹhin.

Siwaju eyi ni ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Alakukọ ti kesi gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ wọn wipe, ki ẹnikẹni ninu awọn ọmọ ẹgbẹ na maşe lọwọ ninu ibo Apapọ ti nwọn fẹ di ni ana.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na sọ wipe "Madaru" wa ninu eto ti awọn enia kan şe lati fi orukọ awọn Aşoju silẹ, ni gbogbo agbegbe na ni nwọn si gbe sọ wipe awọn kan wọle laiko si alatako.

Şugbọn nigbati o di owurọ ana, gbogbo awọn ara Eko, Ọbalende, Ikoyi, Falọmọ, Yaba, Ebute Metta, Apapa, Surulere, Mushin, Shomolu, Ikeja ni nwọn ko jade lati lọ dibo.

Onirohin wa Ejongboro ti o lọ kakiri gbogbo igboro ilu Eko lana fi ye wa wipe gbogbo awọn Ẹleran Alatẹ, oniwosiwosi, Alaşọ Alata Eleweọmọ, ni akotan, gbogbo awọn obinrin ọlọja ni Ebute-Ero Ereko Ọbun-Eko Ita Faji Jankara, Sangirosi, Idẹra Kajọla ni gbogbo wọn ko wa si ọja lana.

Bakanna ni gbogbo awọn Ile işẹ Ijọba dẹ l'Eko ni nwọn ko si şişẹ.

Awọn oşişẹ Bọọsi Munisipa kọ işẹ eile gbogbo wọn ko şişẹ Awọn Oşişẹ ko tilẹ ri mọto wọ de ile işẹ wọn ni ana Takisi ni awọn miran

WO OJU EWE KẸFA

# Asisọ Ọrọ Ni Bamu-Bamu L'ayo

Lati Ọwọ IBAKA

Otọ ri ọrọ awọn ọjọgbọn pe yiyi ni aiye nyi. Nitotọ aiye nyi oorun ka, o si tun nyi ara rẹ ka gẹgẹbi ogo tabi okoto ti awọn ọmọdẹ nfi şire. Şugbọn yatọ si yiyi mejeji ti a f'ẹnu kan wọnyi a tun le sọ pe aiye nyi nigbati igba ati aşa ba nyipada. Nigbati igba ati ihuwasi awa ọmọ enia ba ti yipada tan, owe tabi ọrọ ti o ti jẹ ọlọgbọn ti o si ti ba eti mu tẹlẹ-tẹlẹ ri a wa pada di aşipa tabi aşişọ ti ko ba igba mu mọ. Ọrọ kan bẹẹ ti o ti wa pada di aşişọ ọrọ ni ọrọ orin ti awon ara ilu ma a nfi ilu kọ bayi pe "Bamubamu layo, awa ko mọ pe ebi npọmọ ẹnikọkan, bamu-bamu layo."

Ni aiye atijọ, nigbati imọ titun ti ode oni koi ti waiye rara ni ilẹ Yoruba işẹ ogun jija, igara dida ati owo ẹru ni ọmọ akin nşe jẹun. Nigbana nipa işẹ awọn iwọfa ati ti awọn ẹru ni awọn ti a npe ni alagbara fi ndide ti nwọn si ndi olowo ati ọlọla. Ni akoko ti a nwi yi, a ma a ngbọ iru owe bayi: Ẹja ni ẹja njẹ sanra.

Ni akoko na, ẹni ti o ba gboju, on na ni ayo rẹ njẹ Akoko na ni ọmọde ko gbọdọ nikan rin, nitoripe baba oni-baba ti lugọ sinu igbo lati gbe ọmọ-ọlọmọ ta ra onjẹ fun awọn ọmọ tirẹ. Agbalagba paapa ko le rin lai la okun ipa kọrun nitoripe o le pade akọ ọkunrin ti o ngbe ọkunrin ta jẹun. Ni akoko na ni awọn akọni ile Yoruba a ma jẹ oriki bawọnyi: Aja'le onile bo tirẹ lẹhin. A nle e bọ lẹhin o n'e ara iwaju Awọn ọrọ bi Bamu-bamu layo yi ba ode igba inu. Ọrọ na fẹrẹ jọ ọrọ ti Kaini sọ lẹhin ti o ti lu aburo rẹ Abeli pa tan, ti o si da Ọlọrun lohun pe: Emi ha nşe olutọju arakunrin mi bi? Ako ko ti a nwi yi jẹ aşiko imọ-t ara-ẹni-nikan. Ni asiko na ẹniti a ba bi si ile ọla a tubọ ma lọla si i ni. Ẹni ti a ba si bi ile talaka nşe ni yio tubọ ma giranan si i ninu iwa oşi. Laiye ọjọun, atapatadide enia ko pọ bi ti ode oni.

L'ode oni aiyẹ ti yipada Aiye tidi aiye ẹkọ ọfẹ aiye iwosan ọfẹ ati aiye awọn atapatadide enia Aiye tidi pe ki ọmọ aşẹgita k'o ma ba ọmọ olowo figa gbaga ni awọn ile ekọ giga Aiye tidi ajumosepọ ati akojọpọ ọwọ lafi nsọ aiya Aiye tidi ajumọda ajọ owo ori ninu eyiti olowo yio da gẹgẹbi o ti lowo to ti talaka yio sik iwọn ti agbara rẹ ba gbe kun u Lati ara ajumọjọda owo ori yi nia ti nşẹ icawo ẹkọ ọfẹ ati iwosan ọfe fun mọ talaka Lara rẹ na ni a tl ntẹ titi ọlọda ti aşe omi ẹrọ ti asi tan ina ilẹtirikl si titi fun anfani ọmọ olowo ati ọmo talaka

Ẹnyin ọkawe mi ọwọn ẹ ko wa ri i pe, l'ode oni aşişọ ọrọ ni bi a ba sọ pe 'Bamu-bamu l'ayo, awa ko mọ p'ebi np'ọmọ ẹnikọọkan"? L'ode oni onikaluku ti di olutọju arakunrin rẹ.

Njẹ ki yio jẹ ohun iyalẹnu fun ọpọlọpọ ninu awọn ọdọ wa loni lati gbọ pe ni igba lailai "Bi o ti wu ni l'anşe Imale ẹni" ni ọrọ larin oşişẹ ati ẹni ti o gba a ş'işẹ jẹ? Bo ti wu ki o yanilẹnu to, sibẹsibe otitọ ni pe ara ti o ba wu onişẹ ni o ma nfi oşişẹ abẹ rẹ da nigba atijọ. Iye owo ti o ba wu u ni o nsan fun u Igbati o ba tẹ onişẹ lọrun ni oşişẹ le kuro nf ibi-işẹ. L'ọrọ kan, bi ẹru ni oşişẹ ma nşe fun onişẹ re. L'ode oni nkọ o? Gbogbo nkan ti yipada, Onişẹ ko tun le san iye owo ti o wu u fun oşişe rẹ. Bi o ba da l'asa awọn ẹgbe osişẹ a ka a l'ọwọ ko. Onişẹ kan ko tun le lo oşişẹ rẹ ni ilo eru mọ Bi o ba dan a wo Ijọba ilẹ wa yio sọ fun u pe aki şẹ bẹ

Aye ti oşişe wa si onisẹ rẹ nigba atijọ fẹ alaye diẹ ki o le ye awọn ọmọ ode o ni Nigba atijọ kosi tipe ẹni kan agba şisẹ asegbowo iosoşu labẹ ekeji nipe kl tala ka kio yawo lọwọ olowo ki talaka na kio sidi Iwọfa labẹ olowo na lsẹ aşegan ati ailopin niti Iwọfa tabi aringba yi titi on yio fi san owo pada fun olowo rẹ Nisbati awọn ọmọ olowo rẹ ba nsi mi ninu aba tabi ahere lo ko Iwọfa gbọdọ wa ninu orin nibiti o gbe sisẹ nigbati awọn ba pada lati oko sile ti awon ọmọ olowo rẹ nfi ẹja yiyan bi Iwọfa ba le ri epo fi jẹ işu ki o dupẹ lọwọ ori

Bayi ni aiye ti ri nigba atijọ. Lasiko na ni orin Bamu-bamu layo dun leti. Ko beti mu mọ lode oni. Aiye ti yi kuro nibi iru ọrọ bayi; o si ti yi sibi Fẹran ọmọnikeji rẹ bi ara rẹ,

Bi ọjọ ti ngun ori ọjọ, ti oşu si ngun ori osu ni iyipada yio tubọ ma pọ si i

WO OJU EWE KARUN


AFRICAN SPECIAL

* Full tropicalisation and underbody protection plates
* Strong and comfortable suspension.
* Outstanding road holding.
* Modern workshops and spare parts stores, manned by Factory Trained Staff.
* HIGH RESALE VALUE.

DON'T FORGET THAT YOU CAN ALSO TRADE IN YOUR OLD MERCEDES-BENZ OR RENAULT CAR!

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA, & EBUTE METTA, IBADAN KADUNA, KANO JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT HARCOURT & ABA.

# IWE SI OLOTU

## Şhoyinka Nki Yin O

OLOTU:— Dakun gba mi ni aye ninu iwe rẹ arimslelọ ari yọ kọbọ meji ninu tọrọ lati ki awon onkawe Irohin Imolẹ pe nwon ku Ọdun, nwon si ku iyedun.

Oluwa ko şe Ọdun yi ni od un rere fun wa o Amin.
Mo si tun ki Olotu p a a p a ati awon abasişepo rẹ pe won ku ewu Ọdun yi o. Edumare jẹ ki a şe opo Ọdun l'aiye o
Ileri mi ni ọdun yi lagbara Ọlọrun ati Olotu ni pe, ẹ o ma ka itan. Itumo ala, Itumo Ami Ara ati Owe Ijinlẹ mi bi ti atẹhinwa, nitori idi eyi, mo kesi awọn onkawe wa pe ki nwon ma a ra Irohin Imolẹ deede Ki awon nkan anfani na ma ba ta won o
Emi ni
J.O. Şhoyinka
Onitan Ajiran

Yeosa ni ilu Ibadan.
A si ni lero pe lẹhin ti ẹyẹ oku ti ologbe Şhoyinka na a lero pe onitan wa ọgbẹni Şhoyinka yio si ma fun wa ni itan oloyiomọmọ miran gẹgẹbi ti atẹhin wa ati pe o pe ọjọ diẹ ti a t n ri itan rẹ ka, Olotu mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi ajinde yio ma jẹ ọ
Emi ni
Yẹkini Adeyẹmi
Ibadan.

## Ẹku Idele O Şhoyinka

Olotu:- Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye ranpẹ die ninu Iwe nyin a kọnọ lede ki ọgbẹni J. O. Şhoyinka onita Ajinran ilu awon oku pe ki o ku ilede ati aşẹhiude ti ẹgbẹ rẹ ologbe Jacob Şhoyiuka to şaleisi laipẹ yi mo si baọgbẹni wa J. O. Şhoyinka ati awọn ẹbi rẹ kẹdun pupọ lori iku ti ẹgbẹ rẹ otun rẹ na ku ati pe ki Oluwa si gbe si apa otun rẹ ki o si tọju awọu ọmọ ti o bi silẹ.
Awa onkawe Irohin Imọlẹ ni ilu Ibadan si ba oniwe wa ọgbẹni J. O. Şhoyinka kẹdun pupọ paapa julọ awa ti o ngbe ni lopole

## Itan Shoyinka Nkọ?

Olotu:- Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye ranpẹ ninu Iwe nyin ti nia bi akara gbigbona ku lati bere ogbẹni wa onigeg ku bi ojo ti o tun jẹ onitan Ajinran ilu awon oku ogbẹni J. O. Şhoyinka lori pe o ti pẹ diẹ ti a ti ri itan rẹ ka ninu iwe nyin Irohin Imolẹ ati pe elepi ya awn onkawe Irohin Imolẹ lẹnu lati ri pe a ko ri awon itan ka eyi to jẹ pe o yato si itan Ajinjiran ilu okui
Olotu inu awa onkawe nyiu yio dun bi ẹ ba le jẹ ki a tete tun ri itan miran ka lati owo ogbẹni J. O Şhoyinka ati pe awa si nreti itan rẹ bayi. Eleyi jẹ ohun ti ko dun mo wa ninu pupo. Mo tun ki nyin olotu pẹ ki ẹ ku a bo binajo nyin ati pe mo dupẹ lowo Adele nyin ra pẹlu fun iwe Irohin Imolẹ ti a nri ka nigbati ẹ ko si ni ile.
Emi ni
Adetọla Ilori
Abẹokuta.

---

BERE EGBOGI PATAKI YI TI NWỌN NPE NI:—

## "Apias Reducing Dragees:,

Jẹ ojulowo egbegi ti awọn Jamani şẹş şe iwadi rẹ fun awọn ti o ba sanra tabi ti o ba 'TOBI, ju latima mu ki nwọn le fọn tabi ki wọn fọnku lai si wipe nwọn ma ka ewọ onjẹ ti nwọn yio maa jẹ rara, bẹsi ni ko lewu ni lilo fun enia yala ọkunrin tabi Obinrin rara.
Ki enia şanra, gborin, tabi kio tobi pupọju ki nşe ohun ti o dara o si lewu pẹlu ọpọlọpọ amodi ni o nko A ya lilu kiki tabi jija nigbakugba aikole mi kanlẹ daradara, ara wiwo tabi wiwuwo; Eemi mimi họ-họ ati orişirişi amod omiran pẹlu
Şa dan Igo rẹ kan wo, Iwọ na yio ri ayipada ati Alaa ti yio de si ọ. Bere ni Şọbu awọu Olori Elegbogi Jamani ni Igboro Ilu Eko.

WATERLOO STORES
8, Palm Church Street, Lagos
ADEDUN CHEMIST
4, Wakeman Street, Yeba

EGBOGI AWỌN ARA ILU FARANSE

## TESSYDRE

Fun Ọmọ — Ọwọ Ati Ọmọde Gbogbo



Tessydre jẹ ojulowo egbogi haunhaun ti meji irufẹ bẹ kosi kakiri igboro ilu Nigeria fun itọju ọmọ ọwọ tabi ọmọde lati le jẹ ki wọn ma hu EHIN ẹnu wọn pẹlu irọrun laisi wahala rara tabi aikole sun yala losan iwe sun awọn iya wọn gbogbo Ogorun orisirisi egbogi bayi ni wọn npolowo sinu ẹro gbohungbohun ati sinu iwe kika lojojumọ şugbọn kosi eyi ta le fi we egbogi Tessd re rara o. Ọlọgbọn di ori ẹja mu pupọ ninu awọn ara ilu Saro ati awọn ara ilu Agọnyin (CHANA) mọ egbog yi dajudaju on na ni wọn si nlọ fun awọn ọmọ ti wọn ba şẹşẹ bi titi fi di nkọn bi ọmẹ ọdun wawa gbako. Kosi wahala tabi iyọnu inu rirun ọka ori inu iwọ aiperi osiinu fẹkun fẹkun ewo, kokoro ara lapalapa ara gbigbona igbẹ şişu, gburu tabi aikolokun ninu ara sisu, Inu kunkun iro afẹfẹfẹ ati orişirişi awọn amodi tabi aisan ti o ma nyọ awọn ọmọ ọwọ lẹnu nigba Ehin HIHU" gbogbo. Tessy dre a ara mu ki ehin ẹnu rẹ ọmọ rẹ lagbara gidigidi ati san a wọn pẹlu.
Awọn ọmọ ti wọn nlo egbogi yi ki saba şe ama rara niwọn igba ti wọn ba ti ngbọsẹ dede, ti otutu ko si le ri aye lati duro ni igbaya wọn ti wọn jẹun dara ara ti nwọn si nsun gbadun pẹlu
Bere Egbogi Ni Şọbu Awọn:—
Waterloo Medicine Stores,
8, Palm Church Street, (Ọja Ita Faji
Lagos. Nigeria.
ADEDUN CHEMIST
14 Wakeman Street Yaba

---

## Ipolowo Ọja Rẹ Ko Ti Yege

Nitoripe
O KO TI POLOWO ỌJA RẸ
SINU
IROHIN IMỌLẸ
T'ODUNKA FUN GBOGBO YORUBA
KỌWE IPOLOWO ỌJA RẸ SI
ADVERTISMENT MANAGER
IROHIN IMỌLẸ
16, Bamgbose Street Phone 21985

# YE IRAWỌ RE WO

AGUARIUS (Jan 22 - Feb 20) Ire wa fun ọ loni, ki o si gbajumọ Işẹ rẹ, ki o lọ şe abẹwo awọn ti o nifẹ rẹ ki o si fi ọrọ wa ọrọ lẹnu wọn, awọn ẹbi rẹ ati awọn ọrẹ rẹ yio ma nifẹ rẹ siwaju.

PISCES (Feb 21 - Mar 20) Maşe jẹki irẹwẹsi ọkan mu ọ loni, ododo ni ohun ti o nfẹ mọ, şugbọn koiti si aye lati si paya nkan na.

ARIES (Mar 21 - April 20) Arẹ wa lara rẹ maşe fi ara silẹ pupọju Işẹ yo gbe ọ lọ si irinajo kan, ire si mbẹ pẹlu rẹ loni.

TAURUS (April 21 - May 20) Ki o şe irohin aladun kan ti o dara nipa işẹ li o jẹ eyi o dara fun ọ.

GEMINI (May 21 - June 21) Işẹ aje rọgba yi ọ ka ohun ti o si fẹ bẹrẹ ti o jẹ ti ara rẹ, yio ba ode pade Iwọ yio gba alejo lati okere, ọrọ işẹ kan yio si şẹlẹ

CANCER (June 22 - July 22) Şe jẹjẹ, ki o si bẹrẹ diẹdiẹ ti o ba ti mọ O lẹ da arẹ bo ọ, tobẹ ti o fi ledija larin iwọ ati ọrẹ rẹ kan, igbadun ati ayọ yio wọ ile rẹ loni.

LEO (July 23-Aug 22) Ijade rẹ loni yio dara ni wiwo nitori ire mbẹ ninu rẹ Bio ba si lọ ra ọja loni iwọ yio ti ere jẹ pupọ ninu rẹ Şugbọn maşe hawọ fun ẹnikan

VIRGO (Aug 23-Sept 23) Maşe ba ẹnikẹni gbolonun aşọ loni maşi şe gbagbe awọn ti iwọ pẹlu rẹ jẹ ọrẹgbiyan u diẹ tio ba şe yio mu ere nlala wa

LIBRA (Sept 24 - Oct 23) Ori rẹ yio ma gbona lakoko, ohun ti o dara ni wipe ki o maşe ba ẹnikan gbonu ninu awọn to sunmọ ọ, eto ti o si fẹ fi to işẹ rẹ yio yọri si rere.

SCORPIO (Oct 24 - Nov 22) Niti işẹ şişe, o mọ daradara, şugbọn o kanna biẹ. Tọju işẹ rẹ na, jẹki iwọ pẹlu ọrẹ rẹ jijọ kẹsẹ lọ si ode loni, si awọn oni baba rẹ.

SAGITTARIUS (Nov 23 - Dec 21) Ẹlẹda rẹ yio dabo bo ọ loni, larin iwọ ati ọrẹ rẹ, ki o si ma si şe tun da ija silẹ, foju silẹ si işẹ rẹ ki o si ri pe gbogbo rẹ nlọ leto - leto.

CAPRICORN (Dec 22 - Jan 21) Ri gbangba wipe awọn işẹ tI o şe ku yanri si rere ki o to wa dawọle işẹ miran maşe ba aladugbo rẹ ja şugbọn ki o ma fi ifẹ ba wọn gbe.

# Gbejẹ Ki O Niyi

## Lati Ọwọ Emmanuel oloto-Ilu Omupo

Gbe jẹ ki o niyi ọrẹ mi Ẹ ni aiye nyẹ loni:
Kio dakun ki o şe ara rẹ jẹ jẹ.
Ẹ ni igba si ndun fun yenyen.
Kio jare ki o fi ara re siwọn

Ile aiye ki işe awe ilọ ilu Rara.
Ọrun nikan ni arẹmọbọ
Ọmọ ti a bi loni ti o si di Ajikẹ.
B'o şe were ad'ẹni iku npa
Bẹnsini ọpọ enia atata
Ti aiye nyẹ ti ẹda si nfẹ
B'ọpẹ titi nwọn a d'ẹni iku mu lọ.
Ko si ş'ohun ti nwa ti ki nkan l'aye.
A fi ọla Ọlọrun ti oto wa jẹ
Bi on'irinwo ẹru loni ti oko gbe jẹ.
Bi o si ni Gbingbin-nikin ọrọ ti o ko şe pẹle.
B' oşe were nwọn a salọ bi eiye.
Bi o ni wọn ma şeiGberaga Gbe jẹ ki oni 'iy ọrẹ mi
Igba agbejẹ ki ifọ kiakia,
Awo ogbejẹ ki ifaja bọrọbọrọ.
Şugbọn ero to fi waduwadu Ko ai jẹ ma ya ti ko gbejẹ
B'opẹ titi a d'ẹni aiye ntẹ kiri.

Yọyọ l'ẹnu aiye yọyọ l'ẹnu enia;
Ẹni t' o npọn ẹ loni ti o yọ titi
B' o şe were a bu ọ lola b'ẹni layin.
Şe ọgbọgbọ iyawo mbọ wa d'otuba - ntẹ,
Gbe jẹ ki on iyi ọrẹ m aiye n'ipa, aiye nipọn.

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TỌNIC

ALE-BI-ALE Egbogi Tọniki Jamanu titun ti gbogbo ara ilu Eko ati Jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan işẹ rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo.



Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala lala şişe ti o ko le jẹun daradara, tabi ki o male sun dada ọkun lọsan tabi awọn işan ara rẹ gbogbo ko ba şişẹ daradara ti Eemi Breath) inu rẹ ko ba gunlẹ daradara fun işẹ tabi wahala şişe tabi fun awọn ailera gbogbo' tabi ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja ọgbọn ọdun o si de adọrin tabi jubẹ lọ. Mọ daju pe "DYNAMIREN ni egbogi ti o nfẹ lati sọ'ara rẹ di ọtun pa tapata ara rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ tio ti hunjọ yio yi po pada patapata alafia ati gbadun yio de si ọ Iyẹn bẹ.

Bere egbogi na ni Şọbu

NIGERIAN MEDICENE STORES
4, Tinubu Square Lagos
ATI NI ŞỌBU
OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA
IBADAN

## Gbanjo ! Gbanjo ! !

FUN ỌDUN KERESIMESI

A ni lati fi kede fun awọn onibara wa pe Ọja gbanjo wa bẹrẹ lati oni lọ titi di 30/11/64. Tete ra tirẹ ki o to kasẹ nilẹ

APEJUWE ILE ITA IWE WA

Wọ Bọọsi Mushin, sọkalẹ ni Atẹwọlara Bus Stop Bere ladipọ Street, ti o ba rin titi Ladipọ, bere ILE IWE ODU - ABỌRẸ. Ti o ba de ibẹ tan, wa be re Nomba 5, Alaba Stree Mushin, ile işẹ wa dojukọta ODUS SURF"

AWỌN WA

Olubori Egbogi Ajẹbidan 40s di 30s Iwe Egbogi Ajẹbidan 25s di 22s Iwe Egbogi Awogba Aruu 20s di 17s Iwe Ilana Ifa purin titẹ ati etu şişe 20s di 17 Iwe Afoşẹ Isẹdalẹ Yoruba ati Psalmu Ajẹbidan 3/6 di 2s 6d Turari Isẹgun Ajẹ 10s 6d di 8s Turari Itaja 10s di 6d 8s Turari Ala rere 10s 6d di 8s Iye owo Turari pangolo niti oke yi Turari ti o wa ninu pakẹti jẹ 2s 6d pere Iwe Itumọ Ala Joseph Alala 5s Iwe Aniyan eto Irun o ti di 2s 6d Akọnni lẹsin pataki Islam 2s 6d Tailor's Measurement book dI Is 6d

Tenants Agreement Forms 10/6d dl 5/ Gold Smith Form.s
Certficate of Apprenticeship (mẹta) 17/6 di 10/6d

ỌJA TITUN TI A ŞẸŞẸ RI GBA

Abẹla mimọ fun adura tete Idaloju (orişirişi awọn fun Turari.
abẹla mimọ fun itaja (Kowo wọle pẹlu Turari 20/-
„ „ „ Işẹgun Ajẹ pẹlu Turari 20/-
Lọfinda tabi Ororo ipara fun itaja, Işẹgun Ajẹ ati arisikl 30/- Igo kan

Fi owo ranşẹ tabi ki o wa ra ni ọdọ:—
J. O. Shoyinka
5. Alaba Street
MUSHIN.

## Ayọ ayọporo ni Akere yo nijosi ti o fi Ṣẹ Ni Itan

Lati Ọwọ ẸṢỌ .

Nigba atijọ Ọba ilu kan wa ti nwọn npe ni Onișin, o ni okiki, o li ọla, o si ni dukia lọpọlọpọ ko si ogun ti yio lọ ti ko ni ṣẹgun ilu na, nitoripe, o ni awọn enia pupọ lẹhin rẹ. Ilu Iṣin jẹ ilu nla, o si ni ọja nla, ojojumọ ni awọn alejo nwọ inu rẹ.

Ni ọjọ kan irohin kan wipe Ọba Onișin wọ aja. Awọn agbagba ilu Iṣin pe ara wọn jọ lati da Ifa wo, tani ki nwọn fi rọpo Ọba to ku, Nwọn difa lọ, nwọn difa bọ, Ifa sọ wipe Akere ni ki wọn fi jọba na.

Ọmọba kan wa ti o jẹ wipe on ni Abikẹhin fun Ọba Onișin Akere si ni orukọ rẹ njẹ. Ha! si ṣe gbogbo enia wipe, Akere ti o jẹ ọmọ kekere, alagbara ati janduku enia ni ki nwọn wa fi jẹ oye ọba. Gbogbo awọn agbagba panupọ wipe ayafi bi nwọn ba tun ifa na da.

Nwọn ranṣẹ lọ pe Adifa Koro, Awo Ipọnrin ki o wa tun Ifa na da fun wọn. Wayi ! ti nwọn tun da ifa, Akere ni Ifa tun mu, ṣugbọn awọn Ijoye ilu ko fẹ ki Akere jẹ Ọba le wọn lori, nitori nwọn mọ iru itu meje ti Akere nṣe larin ilu.

Awọn agbagba ilu ko gba ohun ti ifa wi, nwọn ṣe eti gbọnran si ẹbọ, nwọn ṣe arọngbọ si eṣu, nwọn ni bi iwa ẹni ba baje, owo ara ẹni li a fi ntun iwa ẹni ṣe, ni gbati Ifa ti mu Akere, ni o ti lo gba ilu gang an sẹhin ti njo ti o si korin bayi wipe;-

Akere yio j'Onisin
Akere yio j'Onisin

O bẹrẹ si jo kakiri ilu isin bio ba jo diẹ asi fo si ke lai nigba bibẹrẹ si fo bayi wo iwaju rẹ bio tifo fẹrẹ bẹni o ṣubu sinu koto osi fi itan ṣẹ

Awọn gbogbo Ijoye ran ṣẹ lọpe Araba Ita layi owo gbulu gbulu ku kio wa yẹ Ifa tirẹ wo fun wọn B i o ti o gbe Ifa t rẹ janlẹ o si yan ẹlomiran ni Ọba Onișin bayi ni akere i ayọ ayọporo gba oye Ọba kuro lori ara rẹ nitori a ko gbodọ fi alabuku ara jẹ oye Ọba akere tiṣẹ ni tan ko le jọba ni Akere ba kọsẹ sinu igbo loba di kọn kọ ti nwọn pe ai Akere

Eyi na li o di owe ti wọn npa wipe ayọ ni Akere yọ ti o ṣẹ ni itan

---


## Ogun Belubelu Tabi Lẹrẹ

ỌNA ỌFUN — ỌNA ỌRUN

Eșu nlanla ni lati fi abẹ si ọfun lati ge Belubelu o ti fi iku pa ọpọlọpọ enia nipa bayi ati 'an Ogun Ajẹbidan ti ati fi wo Ogunlọgọ enia san ni ọjọ kan na. Ko Si Tun Se Oluwarẹ M ọ Lailai,

Ẹ BERE LỌDỌ

### Ọgbẹni Aro - Lambo

43, Koseh Street, Lagos.

A DAYS REMEDY FOR THE CURE OF

### TANSILITIES

WITHOUT OPERATION

### Price 12s 6d

---

## Kini E Nduro Fun ?

Bi o ba ni asọ fun fifọ ati lilọ bi (wollen) asọ oke, Tapẹta Sapẹti ati orișiriși asọ ti o ba ni fun fifọ atililọ ni i-ẹju kan

TETE GBE WA SI ỌDỌ

### JOYCE L UNDRETTE SEVICE

34, Ojo — Oniyun Street,
Apapa Road Ebute Mẹtta

Kia ni ao ba ọ fọ ti o si ri gba ni ẹsẹ kanna. A .e wa gba ni ile rẹ, ki a si ko pada fun ti a ba fọ tan kọ nomba ile rẹ ranṣẹ si wa.
Dan wa wo lẹkansoso ki o si ri bi iṣẹ wa ti dara to wo pọkọ ni ẹ si ngba


---

LATI OJU EWE KEJI

orilẹ aiye. Bi iyipada wọn yi ba si ti npo si i, bẹ na ni awọn asa ati awọn owe atijọ yio ma di kasi, ti nwọn yio si ma a jasi așiṣọ ọrọ.

---


# EGBOGI JEDIJEDI

BERE EGBOGI



Aworan ẹgbẹ yi fihan gba gba ibiti Jẹdijẹdi rẹ wa ni ara rẹ ti nyọọ lẹnu nigba gbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu tabi iho idi enia ibiti a ma ngba ṣe igbonșẹ Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun' ọkunrin ti o si soro pupọ lati ṣe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni o wa ti nta kakiri ode nisisiyi an nwọn ma a npolowo nw un iwosan rẹ ṣugbọn boy fa le i ri mewa ninu awọn ogun ti o le ṣe iwosan aru

### CYCLOVEN

yi daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe boya ti wọn gbe lọ si ile iwosan lati lọ ṣe eyiti o bi nṣọ jade omusu ku nipa be awọn o bọ lọwọ rẹ patpata

Ṣugb n awa ko ro bẹ rara lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun bẹrẹ bakana Orisirisi Jẹdijẹdi ni o wa Ekini ti o bẹrẹ nipa aiko ma ṣe igbọṣẹ dede tabi lojojuma ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna pupọ ojojumọ abi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu) pupọ ẹlomiran ẹwọ eran Ṣuga oniruru ohun adidun pupọ, pupọju nigbu kugba Jẹdijẹdi orisirisi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ sode ninu o uṣu tabi ti o ba nmu ẹjẹ walẹhin igbọnșẹ tabi ti o ba nyọ ti o ba ṣe igbọnșẹ tan ni tabi ti nrin ọ ninu omuṣu ni eyikeyi ti o ba jẹ bere egbogi CYCLOVEN ati awọn Oyinbo Jamani ṣẹṣẹ wa idi rẹ kio si danwọ kuaju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijẹdi patapata alafia yio de ba ọ ekeji rẹ ko si ninu gbogbo awọn ni a tan igboro Naijiria bere ni :

NIGERIAN MEDICINE STORES
4 Tinubu Square Lagos
WATER-LOO MEDICINE STORES
8, Palmchurch Street, Lagos i
Phone :- 22678 Nigeria, (Ọja ItaFaj

---

BERE EGBOGI PATAKI YI TI NWỌN NPE NI:-

## "Apias Reducing Dragees:,

Jẹ ojulowo egbegi ti awọn Jamani ṣẹṣ ṣe iwadi rẹ fun awọn ti o ba sanra tabi ti o ba 'TOBI, ju latima mu ki nwọn le fọn tabi ki wọn fọnku lai si wipe nwọn ma ka ewọ onjẹ ti nwọn yio maa jẹ rara, bẹsi ni ko lewu ni lilo fun enia yala ọkunrin tabi Obinrin rara.

Ki enia ṣanra, gborin, tabi kio tobi pupọju ki nṣe ohun ti o dara o si lewu pẹlu ọpọlọpọ amodi ni o nko Aya lilu kiki tabi iija nigbakugba aikole mi kanlẹ daradara, ara wiwo tabi wiwuwo; Eemi mimi họ-họ ati orișirișì amod omiran pẹlu

Ṣa dan Igo re kan wo, Iwọ na yio ri ayipada ati Ala- a ti yio de si ọ. Bere ni Sọbu awọu Olori Elegbogi Jamani ni Igboro Ilu Eko

WATERLOO STORES
8, Palm Church Street, Lagos
ADEDUN CHEMIST
4, Wakeman Street, Yaba

---

## KERE O!

Kurani Ọgbọn Eṣu ti a ṣe Larubawa ati itumọ ri sinu Yoruba 25/- Postage 1/6d, Iwe Adura patak de Ariski ati iṣẹgun lori ohun gbogbo lati ilẹ Mi ra 1/6 Iwe Atumọ Ala ati Adura Ala ibanujẹ a ti nta ni 4/- o ti din si 2/6d Afọmọ isin Mohammed 1/— lọdọ:—

Tete ra tirẹ

ẸS KOGBOGUN SERVICE
8 Idumagbo Avenue, Lagos Nigeria
(Leti Ọja Jankara ...)

